**Lakaye ọrọ**

Ẹniti a ba mbawi ti o nwa ọrun ki, yio parun lojiji, laisi atunṣe. Nigbati awọn olododo wa lori oye, awọn enia a yọ: ṣugbọn nigbati enia buburu ba gori oye, awọn enia a kẹdun.

# Irohin Yoruba

A Newspaper of the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd

VOL. XXIV NO. 686. JULY 21— JULY 28, 1958. KỌBỌ MEJI (2D.)

**OWE**

Bi agbalagba ba nyọ ilẹ da, ohun buruku a ma a yọ ọ ṣe.

# AWỌN ONIṢẸ ỌKỌ OFURUFU FI ẸYẸ NLA PADE OLOYE AKINTỌLA

EKO—NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni awọn Ẹgbẹ Oṣiṣẹ Ọkọ Ofurufu wa fi ẹyẹ nla pade Oloye S. L. Akintọla, Minista Alamojuto Iṣẹ Waya ati ti Ọkọ Ofurufu fun Apapọ Ijọba Naijiria nigbati o gun'lẹ si Ikẹja lati inu ọkọ-ofurufu ti o gbe e bọ lati ilu Oyinbo nibiti o gbe ti lọ ṣe eto adehun pẹlu awọn Alakoso Iṣẹ Ọkọ-ofurufu (BOAC) ati awọn Alakoso Iṣẹ Oju-omi (Elder Dempster Lines Ltd.)....Nitori awọn Alakoso Ile-iṣẹ mejeji yi ni o fẹ jẹ alabapin ninu iṣẹ ọkọ-ofurufu ti Apapọ Ijọba Naijiria fẹ da silẹ.

Bi ọkọ-ofurufu ti o gbe Oloye na bọ ti nrababa lati ba'lẹ ni awọn Ẹgbẹ Oṣiṣẹ na ti o le ni ọgọdun enia ti bẹrẹsi yombo Minista wọn bayi wipe: SLA! SLA!! SLA!!! titi o fi gun'lẹ, ti Oloye na si sọ kalẹ ni ariwo yi fi gbọjikan ni ebute ọkọ-ofurufu Ikẹja. Awọn Ẹgbẹ Oṣiṣẹ na si gbe awọn paali fẹrẹgẹjẹ-fẹrẹgẹjẹ dani ti nwọn ti awọn ọrọ akọle bayi si "Kabọ o, Oloye S. L. Akintọla." "Awa Ẹgbẹ Onisẹ Ọkọ-ofurufu ki Akintọla kuabọ". "Ebi npa wa ku lọ." "A nfẹ eto owo-oṣu titun" "Funwa ni anfani itọju ilera lẹkunrẹrẹ."



Oloye S. L. Akintọla

* * *

Ọgbẹni T. A. Barber ti iṣe akowe awọn Ẹgbẹ Oṣiṣẹ na si ka iwe-ayẹsi ikini-kuabọ ti awọn Ẹgbẹ Oṣiṣẹ na fun Oloye S. L. Akintọla fun un.

Awọn koko ọrọ ti o wa ninu iwe-ayẹsi ikini-kuabọ na ti awọn ẹgbẹ na nro Oloye Akintọla lati ṣe nipe, ki iṣẹ ọkọ-ofurufu (WAAC) yi jẹ ohun ti Ijọba yio mojuto dada ti nwọn o si ṣe eto ti iṣẹ na yio fi ni anfani dada "Bibẹkọ a ko ni ni irẹpọ kan pẹlu Iṣẹ Ọkọ Ofurufu (WAAC) tabi ti Ẹgbẹ Ọkọ-ofurufu titun ti nwọn tun fẹ da'lẹ".

Nnwọn tun sọ sinu iwe-ayẹsi ikini-kuabọ na pe bi Alamojuto Iṣẹ Ọkọ-ofurufu yi ti pinnu lati tu Ẹgbẹ Ọkọ-Ofurufu "West African Airways Coporation" ka ti nwọn si fẹ fi "Nigerian Airline" rọpo rẹ, a fẹ ki o jẹ pe labẹ akoso Ijọba nikan ni yio wa bi ti Ilu Ghana ati Sierra-Leone (Saro).

Wo oju ewe kejila

## Gomina Agba pada de si Naijiria

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹrindilogun oṣu yi ni Ọlọla James Robertson, Gomina-Agba Apapọ Ijọba Naijiria pẹlu Aya rẹ pada de si Naijiria lati ilu Oyinbo nibiti o gbe lọ lo aye isimi oṣu mẹta. Awọn ti o lọ pade rẹ ni idiko ọkọ-ofurufu ni Ikẹja ni Alhaji Abubakre Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria ati Ọlọla Ọmọ-Ọba Adetokunbọ Ademọla, Ọga Adajọ-Agba Apapọ Ijọba Naijiria.

## Oloye Fadayiro ti ilu Oyinbo de

EKO.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni Oloye E. A. A. Fadayiro, Aṣoju Ẹgbado ninu Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ba ọkọ-elefin M.V. "Accra" de si ilu Eko lati ilu Oyinbo ti o ti lọ lati bi oṣu mẹta sẹhin.

Ohun pataki ti o lọ ṣe ni ilu Oyinbo nipe awọn Olotu Igbimọ Ijọba Gẹẹsi ni o fi iwe pe e ki o wa fi oju si bi awọn Igbimọ Ijọba Gẹẹsi ti ṣe nṣeto iṣelu wọn si lọhun. Gbogbo eto na ni o si f'oju si fun gbogbo igba ti o wa lọhun, o si so wipe on ri ẹkọ iṣelu kọ nibẹ lotitọ ti o le ṣe anfani fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ati fun gbogbo Naijiria pẹlu.

Wo oju ewe kejila

## Azikiwe fẹ wa a ri Balewa

ẸNUGU.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni Ijọba Ila-Orun ṣe ikede ni Ẹnugu pe Dọkita Nnamdi Azikiwe, Olori Ẹgbẹ Alakuko ati Alakoso Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun pẹlu awọn Minista rẹ mẹfa yio fi Port Harcourt silẹ ni ọjọ kejidinlọgbọn oṣu yi lati wa ṣe ipade pẹlu Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Igbimọ Ijọba Naijiria.

Ipade yi ni yio jẹ akọkọ ti Dọkita Azikiwe ati Alakoso Igbimọ Apapọ Ijọba

Wo oju ewe kejila

## Mbadiwe tu aṣiri awọn s'oke-s'odo aṣiwaju Ẹgbẹ Alakukọ

EKO.

LATI igbati ede-aiyede ti bẹ silẹ larin Dọkita K. O. Mbadiwe ati Dọkita Nnamdi Azikiwe, Olori Ẹgbẹ Alakukọ ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun ti nwọn ti mba ara wọn ja ajaku-akata ni Dọkita Mbadiwe ti nṣe ileri pe bi Dọkita Azikiwe ko ba tete ju ọwọ silẹ, bi o ba fi di ọjọ kẹdogun oṣu ti a wa yi on yio fọ igba-ayanga mọ ọ lori.

Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni Dọkita K. O. Mbadiwe, Olori Ẹgbẹ Atunto Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC Reform Committee) pe ipade awọn oniwe irohin. Ninu ipade yi ni o gbe ti tu aṣiri awọn ṣ'oke-ṣ'odo aṣiwaju Ẹgbẹ Alakukọ ti awọn ti jijọ panupọ lati se Atunto Ẹgbẹ Alakukọ nipa siso fun Dọkita Nnamdi Azikiwe pe ko fi aye Olori Ẹgbẹ Alakukọ ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun silẹ.

Ninu iwe yi ti o gun to oju ewe mẹrinla ti gbogbo rẹ si jẹ wipe orişirişi ẹsun ti nwọn fi kan Dọkita Azikiwe ni o wa nibẹ, awọn Minista Apapọ Ijọba Naijiria ati awọn Akọwe Iriju awọn Minista ti nwọn jẹ ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti o f'ọwọ si iwe na ni Dọkita Mbadiwe, Oloye Kọlawọle Balogun, Oloye Festus Okotie-Eboh ati Aja Wachuku pẹlu Ọgbẹni H. Ọmọ-Osagie U. O. Ndem, Oloye O. Oweh, Ọgbẹni O. Bademosi, Ọgbẹni D. C. Ugwu ati Ọgbẹni O. Offoh. Awọn Minista meji ti o ku ninu ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ ti ko f'ọwọ si iwe na ni awọn Ọgbẹni R. A. Njoku ati J. M. Johnson nitori ti nwọn lọ si idalẹ ni aseko na.

Wo oju ewe kẹta



Dọkita K. O. Mbadiwe




# Ẹ MAṢE TU AMURE IGBAGBỌ NYIN SILẸ NI IGBAKAN

KI nto ma a ba alaye mi bo nipa Ọrọ Ọlọrun ti o tọ ki a ma a fi ṣe okun ẹmi wa nigbagbogbo, mo ni lati kọkọ dupẹ lọwọ awọn arakunrin ati arabirin ninu Oluwa Evangelist Joseph Akande II Ogbomọsho ati Elizabeth Olukayode Ademuyiwa (ti a mọ ni Omidan Alice Jokotade ninu iwe "Irohin Yoruba)... Mo si ki nwọn ku ọfọ Baba wa ninu Oluwa, Oluogbe Samuel Idowu Ajibinrere. Ki Oluwa ki o fi orun kẹ ẹ o, ki awa yoku ti Olorun si da si le mọ riri anu Ọlọrun na lori wa

## Lati ọwọ Olumuyiwa Shodẹinde, General Hospital, Gusau

Enyin ara ninu Oluwa, ko yẹ ko jẹ pe ojojumọ ni a o ma a ran wa leti iṣẹ igbagbọ wa, toripe ẹnu wa ni a ti fi jẹ ẹjẹ ki Alufa to bu omi le wa lori pe:—"a o kọ Eṣu ati gbogbo iṣẹ rẹ silẹ", ṣugbọn gẹgẹbi gbogbo nkan ti nlọ siwaju nisisiyi, o dabi eni wipe ọpọlọpọ awọn Onigbagbọ ni nwọn ti gbagbe iṣẹ isin wọn ti nwọn si ti tu amure igbagbọ wọn sọnu ni gerẹ ti a ti baptisi wọn tan. Ti o jẹ pe iṣẹ Eṣu ti nwọn ni nwọn kọ silẹ yi ni nwọn tun nṣe, otile ka ẹlomi lara to bẹ ẹ gẹ ẹ ti o fi ma a wọ ile alawo, onişegun adahunṣe kakiri lati le jogun aiye bi ọkan wọn ti nfẹ.

Nigbati iru awọn eni bẹ ẹ ti o pe ara wọn,ni Kristieni ba pẹhinda kuro lọdọ babalawo tabi adahunṣe na tan, gbogbo awọn enia ti o ri wọn nibẹ a ma a wa fi wọn ṣe yẹyẹ pe bẹ ẹ iru awọn eleyi pe ara wọn ni Onigbagbọ? Inu awọn adahunṣe paapa a si ma a dun si i wipe, awọn ti nwọn pe ara wọn ni Kristieni na ni nwọn tun nwa si ọdọ awọn wa gba itẹbomi iborisa yi. Ki iṣe oruko nikan ni a nlọ gba nibi itẹbomi, fun iyipada lati di ọmọlẹhin Kristi ni ati lati gbe ihamọra wa wọ fun iṣe igbala lati ma a yi gbogbo awọn Keferi lọkan pada ni, gẹgẹbi Paulu Apostelli ti ṣe sọ fun wa ninu Iwe Romu ori 15 ẹsẹ 11 de 14

Ṣugbọn bawo ni iru awọn enia ti nwọn pe ara wọn ni onigbagbọ ti nwọn si nto ọna Keferi ati awọn Aborisa le fi ni itẹlọrun ati ilosiwaju ni igbesi aiye wọn? Awọn ẹni ti nwọn ngmọọmọ tapa si egun eṣuṣu, ti nwọn wa nṣe lakalaka kiri wa ẹniti o ba wọn yọ egun na. Ṣugbọn ibikanṣoṣo ti iranlọwọ a ti le yọ egun na wa, nwọn ko gba ibẹ, ibe na si ni ọdọ Jesu Kristi Ọmọ Ọlọrun. Nitoriti o ti ko wa wipe; "gbogbo enyin ti a di ẹru wiwo le lori ati ti orugbẹ ngbe, ẹ wa sọdọ mi, emi yio si fun nyin ni isimi".

Ki a le ba Eṣu jagun, ki a si le ṣegun aiye bi Jesu ti wipe, "ẹ tujuka mo ti ṣegun aiye na", a fi bi a ba gbe ihamọra igbagbọ wọ, ti a ko si tu ọja amure wa silẹ nigbakan. Ṣugbọn ti enia ba fi gbogbo ọna ẹsin rẹ da agunla, ibanujẹ, aibalẹọkan ogun-nile-ẹru-l'ode ati gbogbo ohun ibanujẹ wonni ti ki i jẹki enia le roju raye ko le jinna si ẹniti o ba ti tu ihamọra igbagbọ rẹ silẹ. Nibiti Ẹmi Ọlọrun ba wa nibẹ ni itẹlorun ati ominira gbe wa. Ẹ wo Iwe Korinti Keji ori 3 ẹsẹ 17.

Ma a siṣẹ lọ, ma a yọ
pelu
Lehin iṣẹ 'wọ o simmi,
O fẹrẹ gb'ohun Jesu na,
Y'o ke tantan pe "Emi
de".

Ki a ranti pe, ki a ma ba ni iyonu tabi wahala laiye ni Ọlọrun ṣe fi Ọmọ bibi inu Rẹ nikanṣoṣo fun wa lati wa ṣe etutu fun ẹṣẹ wa pe "ẹnikẹni ti o ba gba A gbọ ma a ba ṣegbe, ṣugbọn ki o le ni iye ainipẹkun" Ihinrere Johanu ori kẹta ẹsẹ kẹrindilogun. Niwọn igbati a ba si ti gbagbọ, ti a si gba Ọlọrun gbọ tọkantọkan ati Jesu Kristi Ọmọ Rẹ nikanṣoṣo Oluwa wa ko yẹ ki a tun ni iberu ohun ti Eṣu le ṣe mọ, nitoripe a ti ri i pe a ti wa labẹ ojiji Olodumare nibiti Eṣu ati awọn ọmọ ogun rẹ ko gbe le ni agbara lori wa mọ.

Ẹ jọwọ mo bẹ gbogbo enyin Onigbagbọ ti o ba nṣiyemeji lati mura si iṣẹ igbagbọ nyin de aye ti Eṣu ko fi ni le ribi gbe ogun ti nyin. Aguntan ti ko ba duro ni agbo pelu awọn iyoku rẹ nibiti oju Oluṣọaguntan gbe to wọn ni ikoriko nri i paję, nitori ti ẹ ba wa pẹlu Ijọ Ọlọrun nyin l'ọsan l'oru nibikibi ti nwọn ba pejọ si, ẹ ko le ri idanwo ti yio gbe nyin kọja abẹ ojiji Olodumare.

Ni ipari ọrọ iyanju mi si enia gbogbo, ẹ jẹki a fi gbogbo aiya wa, gbogbo ọkan wa ati gbogbo agbara wa fẹ Oluwa Ọlọrun wa, ki a si ni ifẹ ọmọ enikeji wa bi ara wa. Niwọn igba ti a wa ba jẹ pipe ninu awọn ofin wonyi Eṣu ko ni lagbara lori wa. Idanwo kidanwo ti a ba si ri ki a mọ pe Oluwa fi ndan igbagbọ wa wo ni, ti a ba si duro ṣinṣin ninu igbagbọ ti a si ngba adura, a o ni iṣẹgun bi ti awọn eni mimọ iṣiwaju ti ni iṣẹgun lori Eṣu ati Iku.

"Onigbagbọ ẹ jẹ ka
d'amure,
Lati ṣe 'gbagbọ o e.
Igbagbọ yẹ wa, ẹ jẹ ka
mura si.
Ka le gba wa s'ile Ogo
o e."



Aworan oke yi ni ti igbati Alhaji A T Ahmed ti o ti fi igbakan jẹ Aṣoju ninu Igbimọ Ijọba Iwọ-Orun ri nṣe ibura lati di Onidajọ Agba Kotu Ibilẹ Titun (Grade "B") niwaju Ọba Alaiyeluwa T. T. Dada, Ọlọta Ọtta, ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ keje oṣu yi.

Ẹ MA A POLOWO ỌJA NYIN SINU IWE Irohin Yoruba

Ni gbogbo asiko onjẹ
BLUE BAND jẹ onjẹ daradara




O DARA! O Ş'ANFANI F'ARA! O PE!
GBOGBO ONJẸ RẸ NLỌ DARA JULỌ PẸLU BLUE BAND!
BLUE BAND nfun ọ ni ilera ati agbara



FUN
ẸJẸ TO LAGBARA
ATI
AGBARA ỌMỌKUNRIN

HOMMEL'S
HÆMATOGEN

Nwọn se Hommel's Haematogen lati inu EJẸ AKỌ-MALU ti o dara. Yio fun ọ ni ẹjẹ atata ti o ntun ara se ati irufẹ agbara malu.

Nwọn ntọ ọ sinu igo keekeke (8 fluid oz.) ta kakiri gbogbo ile itaja-egbogi,



FUN AGBARA NIBI IṢẸ L'ỌSAN
FUN ALAFIA NINU ISIMI ATI ERE

Ẹ o ri i ra lọdọ awọn aṣoju wa ni Naijiria
ALBAN PHARMACY LIMITED.
2, Victoria St., P. O. Box 461,
LAGOS-NIGERIA.

# IDAHUN SI IBERE ALABI IJỌMU



[illegible]

2

[illegible]

3

[illegible]

## Lati ọwọ Evangelist J. A. Ogbona, C. A. M. Crurch, Mushin



Evangelist J. A. Agbona (Wali Agbaiye Fatra Kal)

[illegible]

OGUNS JUNIOR.

4

[illegible]

5

[illegible]

6

[illegible]



[illegible]



[illegible]

Pastor S. J. Oluwafemi

ARIYESI

[illegible]

(Wa aṣe ewe keta)

**Ẹ ma a ka iwe IROHIN YORUBA nigbagbogbo fun irohin aladun**




Ọna meron ti ASHTON ati PARSONS fi ma n'ra ọmọde lọ ati mọkun:

[illegible]

**ASHTON & PARSONS**




**SUNLIGHT**

**diẹ nfọ ọpọlọpọ aṣọ**

[illegible]




**Ọṣẹ SUNLIGHT**
**—ni o dara julo ni wiwe**

